# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 936 LAGOS SATURDAY AUGUST 29 - SEPTEMBER 4 1964 KỌBỌ MEJI (2D)


# Olosa Fibon Ko Banki Okitipupa, Awon Janduku Ibadan Wewon Apapandodo

OKITIPUPA — Agan bẹ ninu ile ifowopamọ ti nwọn npe ni National Bank ni idi i ana nigbati awọn ọlọṣa mẹwa pẹlu ibọn lọwọ wọn gbe moto akẹru wa si ile banki na, ti nwọn si gbe ẹgbaji pọnun (£4,000) ti nwọn ba lọwọ ọga ile ifowopamọ na lọ.

A gbọ wipe gbara ti awọn ọlọṣa na ti de ibẹ, baba aṣọde ti o wa nibẹ ni nwọn kọ fi aṣọ akisa di lẹnu, ti nwọn si de lọwọ ati lẹsẹ ki nwọn to wọle tọ ọga ifowopamọ na ti o njẹ J.O. Odukọya lọ, ti nwọn si gba kọkọrọ sefu lọwọ rẹ.

Gbogbo owo ti nwọn ba nibẹ ni nwọn gbe lọ bamubamu, nwọn yinbọn si awọn ara adugbo ti nwọn fẹ di wọn lọwọ.

IBADAN—Irohin kan to de ile iṣẹ wa lati Ibadan hi irọlẹ ana ni ti awọn ọganlọgọ awọn janduku ti awọn oṣelu nko kiri ti ọwọ awọn ọlọpa tẹ, nwọn ni ai owurọ kutukutu ni nwọn ti njika wọn mọle, ti nwọn si nfi moto ko wọn lọ si teṣan awọn ọlọpa ni Gbagi. Awọn mejidinlogun ni Adajọ Gomez ju sẹwọn oṣu kọkan ninu awọn bi igba enia ti nwọn ti ko na, awọn miran ti awọn ọlọpa si mbere ọrọ lọwọ wọn si wa ni itimọle.

A gbọ wipe pipa ti nwọn pa okan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ meji kan ni Ijẹbu-Ode

(Wo yoku loju ọwe kẹjọ)

# Oloye Doherty Pe Awon Oniwe Pilot Lejo

EKO — Irohin nla kan ti a gbọ lọsẹ yi ni ti ẹjọ ẹ-ba mi - lorukọ jẹ ti Oloye T. Adebayọ Doherty pe awọn oniwe irohin WEST AFRICAN PILOT ati Ọgbẹni Herbert Unegbu tiṣe Olotu iwe irohin na ni Yaba fun irohin kan ti wọn tẹ jade ninu oṣu yi wipe nwọn ni ki awọn onigbanjo lọ ta ile Oloye Doherty.



Oloye Doherty ni irọ ni ọrọ na, ile Banki kan ko ta ile on rara; o ni fun irọ nla ti nwọn pa mọ on na lati ba on lorukọ jẹ, ẹgbarun pọnun (£10,000) ni on fẹ ki adajọ kotu ganran ba on gba lọwọ awọn ti o ntẹ iwe na jade pẹlu Olotu wọn.

Ọgbẹni O.B Akin-Olugbade ni lọya ti Oloye Doherty gba ti awọn oniwe irohin na, a gbọ wipe iwe ipejọ na ti tẹ awọn mejeji lọwọ: ninu oṣu ti a fe bọ si yi ni wọn yio lọ pade riro ẹjọ na ni kotu nla l'Ọdan ni Eko.

# Alhaji Maito Jalaisi Ni Ilorin

ILỌRIN — Anu ṣe ni lati gbọ iku Alhaji Sule Maito ọkan ninu awọn oṣelu pataki ni Ilọrin ti o jalaisi ni ijẹta, ẹni adọrin ọdun ni, o si ṣe bẹẹbẹ ninu ọrọ ilu Ilọrin ati agbegbe rẹ.

Ni igba aiye rẹ, Alhaji Maito jẹ ọkan ninu awọn enia pataki ti o da ẹgbẹ Talaka Parapọ mọ ẹgbẹ Ọlọpẹ silẹ ni Ilọrin, on ni nwọn si fi ṣe aṣiwaju ẹgbẹ na, awọn ara ilu si fi igba kan yan gẹgẹbi aṣoju si ile igbimọ awọn aṣofin ni Oke-Ọya ni Kaduna.

A ki awọn ẹbi ati ọmọ Ologbe na, nwọn ku aṣẹde Anabi ko gbe Alhaji Maito si afẹfẹ rere.

# Egbe Olomi Fe Yo Azikiwe Kuro Loye Bale

ZARIA — Awọn agbalagba lo npa lowe wipe Ojo ko ba ẹnikan sọrọ, ẹni eji ri leji pa, gbogbo nkan ti eti ti ngbọ, ti oju ti nri ati eyiti o nṣẹlẹ nfi han wa wipe bi ọba tintun ba je ni Israeli ko ni i ọ ẹnikankan mọ.

Gẹgẹbi irohin kan ti a gbọ lati Zaria wa, nagon ni awọn ẹgbẹ Olomi (N.P.C.) ngbero lati yo Dokita Nnamdi Azikiwe kuro loye Bale ijọba Apapọṣe fun ile Nigeria lehin idibo to mbọ yi, bi ẹgbẹ Ajumọṣe tiwantiwa ti awọn ṣeṣẹ da silẹ ba je bori ninu idibo, awọn ẹgbẹ na ni NPC, NNDP, MDF, NDC ati ẹgbẹ NPC ti o wa ni Kaduna ati ọ ri.

Ọrọ yi ni ọmọ ẹgbẹ Olomi kan Alhaji Sani du Zango ti nṣe ọkan ninu awọn igbimọ ti ile aṣofin ijoba ni Zaria sọ ni ...ati o m... awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ soro ni bikan ti awọn npe ni Dongon Bauchi ni ilu Zaria lẹse to koja o si tun sọ fun won pe ẹgbẹ Alakuko ti ṣeto lati yan Ọgọ'a Azikiwe ati Oloye Awoọwọ aṣiwaju ẹgbẹ Ọlọpẹ ti o nṣewọn ọdun mẹwa lowọlọwọ gẹgẹbi awọn Olori agba, o si wi dahun pe "Awa ko ni gba ki eyi ṣẹlẹ nitoripe yio fi ye sile fun aṣẹ adipa"

Alhaji Zango tun ni idibo to mbọ yi yio fi han ẹgbẹ Alakuko ati awọn ti jọmọ se pa wipe aiye ko fẹ won ninu igbo ijelu ni ile Nigeria.

Lẹhin na o wa kesi awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ lati fi iwa imore han si ẹgbẹ Olomi fun awọn nkan daradara ti nwọn ti ṣe fun ... wọn nipa fifi bo wọn fun ẹgbẹ olomi lakoko idibo to mbọ yi.



Oloye SAMUEL LADOKE AKINTỌLA

# Akintola Pelu Faji Sinku Omo Egbe Demo N'Ijebu-Ode

IJẸBU-ODE — Olori pinlẹ Iwọ Oorun, Oloye S.L. Akintọla, ati igbakeji aṣiwaju ẹgbẹ Dẹmọ, Oloye R.A. Fani Kayọde, ogunlọgọ awọn Minisita ilu ati awọn enia ...-jan-an ti nwọn tun re aṣiwaju ninu ẹgbẹ Dẹmọ ...kejado ilu Nigeria ti won ... ẹgbarun enia lọ ni nwọn pese siba sibi eto isinku ti nwọn ṣe ninu Christ Church, Poregun ni Ijẹbu-Ode fun ologbe ọmọba Odufunnade, ọkan ninu awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dẹmọ ni ọjọ Isegun to kọja.

Ologbe ọmọba yi ni awọn janduku ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan fi ada ṣa ni Ago Iwoye ni Ijẹbu-Ode ni ọjọ Aiku ọsẹ to kọja. Ninu ọrọ isinku ti Alufa Michael Arowolo sọ ninu iwasu re lori igbesi aiye ologbe na, o ṣe apejuwe ologbe Odufunnade gẹgẹbi alagbara ati ọni enia ti o ni ode kansoso.



Alufa na tun ni ọmọba Odufunnade fẹran orin kiko pupọ nigba aiye rẹ o si je aṣiwaju ati olufọkansin ọdọda ninu ijọ, ati pe nipa iku rẹ yi, iṣẹlẹ nla ni o jẹ ati adanu ti ko se fenu sọ si gbogbo enia ni ilu.

Ninu awọn ti nwọn fi ododo eloruka se eye ikẹhin fun ologbe na ni awọn wọnyi wa Oloye Iyaafin S. L. Akintọla, iyawo Oloye Akintọla Oloye Remi Fani Kayọde, awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ, ati ẹka re to wa ni Ijẹbu-Ode ati ọpọlọpọ awọn ẹgbẹ miran pẹlu.

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

ELETI—OFE

ti o kun fun irohin aladnu losose

# Awon Ara Ilu Kongo Gbogun Ti Ara Won

LEOPODVILLE — Gegebi irohin ti a ti ngbo tele lati bi ojo melo kan sehin nipa ijagboro to nsele ni Kongo, a tun gbo ti nwon ti gbogbo awon ara ilu Kongo Brazzaville ati Burundi ti nwon wa ni ilu Kongo Leopodville ni ijoba fe le kuro gegebi iwe kan ti nwon te jade ni ilu Kongo Leopodville laipe yi.

Iwe na nfi ye i pe idi ti ijoba fe le won ni nitori iranlowo ti awon ilu wonyi nse fun awon ti nwon ndite si ijoba olu ilu Kongo oniwe irohin kan ni gbogbo awon isura ati ohun ini ti awon ara ilu mejeji wonyi ni ni ilu Kongo Leopodville ni ijoba yio gba lowo won titi di igba ti awon alase Brazzaville ba da ohun ija ti nwon ti gba lowo ijoba Kongo pada fun won.

Nwon ni ile apapo iye owo awon alase ilu Brazzaville gba lowo ijoba Kongo Leopodville ni ebute kan ti nwon npe ni Pointe Noise nigbati nwon nlo si Leopodville ju Oke marun le ledegberin pounu lo (£107,000).

Irohin na tun nfi yewa pe won koti mo iye awon nwon je ara ilu Kongo ti Brazzaville ti nwon ngbe iha Ariwa oorun ipinle ilu Kongo tabi awon ti nwon wa lati Burundi ni ilu ile iha ila oorun ti nwon wa ni Kongo nisisiyi.

Ipinnu ti ijoba Ise lori awon ilu mejeji ti nwon je alajogbo kan a pelu ilu Kongo ni o fi tamo fi ida pelu iroju lori aise dede won ati ajosepo ti o ti wa larin won fun opolopo ojo sehin.

Awon olori nilu Leopodville ni ijoba awon ilu mejeji wonyi ti ran awon olote na lati da ile eko awon soja sile nilu won ati nipa gbigba awon ojongbon iko ilu China laye lati fi orisirisi ohun ija ati imoran se iranlowo fun awon olote na. Lose to koja awon da asoju ilu Burundi to wa ni Leopodville duro lenu ise nwon si dana sun moto adeleer.

# E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

## ELETI—OFE

## ti o kun fun irohin aladun losose




# Nwon Da Kotu Awon Janduku Sile N'Ibadan

IBADAN— Irohin kan de si ile ise wa ninu ose to koja wipe ijoba ipinle Iwo Orun ti da kotu pataki kan sile fun awon janduku ni Ibadan lati mu kiwa iwa janduku, ainani tabi titapa si ofin ti ba le dinku ni Iwo Orun ti Nijiria, Ogbeni E.D. Loremikan ti nse oga awon olopanu fun igberiko ilu Ibadan tun ba oniwe irohin soro lori eto titun yi larin ose to koja.

Ogbeni Loremikan nfi ye oniwe irohin na pe gbigbo ejo to ba je mo ti awon janduku yio ma wa bakana ninu awon kotu kekere beua si ni awon kotu pataki pataki yio wa kakiri, ati pe awon olopa Nairiria ati ti ibile ti sowo po lati gbe ise titun kan de eyiti oruko re a ma je "Afomo ni ti janduku nilu ni ero lati fo ilu mo kuro ninu iwa a na ti ofin ijoba didana sunle onile, ati ole jija ninu idibo to mbo yi.

A tun gbo wipe awon olopa ti bere si se ise na lati ojo Aje lo ni Ibadan, ati pe oga awon olopanu, Ogbeni Loremikan ni ogun logo awon janduku ti won ju bi ogorun lo lati inu orisirisi egbe oselu wa, ti nwon si ti ni ese lodo awon olopa ni nwon ti farahan niwaju adajo ninu kotu pataki yi ni ojo Aje.

O so siwaju ninu oro re pe awon olopa yio era mo mimu awon janduku won yi titi nwon ma fi ri daju pe ko un si nkan bi idamu ati iyonu mo lati ilu ... la oko idibo to mbo ... pe bi awon ba le ni anfani ... ati ma ri bi mefa mu l... jo, o daju pe a nilati ... eyiti o je ti Egbe Olopa ... A aku o ati ti Demo nii ... won.

Nigbati Olola Tafawa Balewa ti sokale tan ni ebute o o furufu ni Ikeja lati Kaduna nibiti o ... ipade kan, o sofun awon to je omo egbe re (NPC) pe awon ti nwon npe iwa julo ni a iwa janduku, awon ... ni nwon ... gbogbo r... e si tun ni ... lati tete tako iwa buruku yi ... ko.

# ELETI - OFE

(A NJU WON KO SE WI LEJO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME
3, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23870

VOL XIV. NO 966 SATURDAY Aug. 29 – Sept. 4 1964


**Oro Olotu:**

# Abiyamo Ku Wahala

Awon Yoruba ni nwon ma nwi pe ABIYAMO KU ORO ti awon ba ri bi iya kan ti nse wahala lori awon omo re. Iwe kan ti okan ninu awon okawe wa ko si wa lori wahala t awon obi nri l'E o ki nwon to fi oru o awon omo sile fun eko ofe ni o jeki a so oro Olotu wa tose yi ni abiyamo ku wahala nitoripe eto iforuko sile awon omode na ko ba oju mu rara.

Nitoto bi enia ba de adugbo ilewe ti awon Ijoba tokasi wipe kawon obi na lo foruko awon omo sile fun eko ofe, oluware yio ri wipe wahala awon abiyamo na po pupoju Lati oru oganjo ni nwon ti ngbe emi lo sun sibe ki awon tisa ba le tete da won lohun nitoripe nwon le so wipe nwon ti pe. ko s aye mo.

Ni Ibadan ni ibiti eko ofe ti bere ni ile Nigeria nwon nkan bi osu kan gbako ni awon eleto iforu o sile na nfi sile fun awon obi lati wa foruko awon omo won sile. Kini fa oro pajawiri tilu Eko? Boya o le je wipe oro ti awon kan mo'nso wipe gbogbo nkan ara Eko ni o yato ni o fa oro iforuko sile pajawiri yi.

Awa oniwe irohin ELETI-OFE be awon al mojuto eko ilu Eko ati agbegbe re ki nwon ro eto iforuko sile awon omode se, ki nwon fi ojo meji meji sile ninu ose kokan, ki awon obi le foru o awon omo won sile larin osu kan ki ider le ba awon omo na pelu awon iya won.

# Iwe Si Olotu

## Awon Ara Amerika

Olotu e jowo e le la idi oro yi ye mi ni alaye nitoripe ko si eniti o gbon tan. oro na ti wa lori okan mi ti pe.

Ibere oro na niyi: lati igbati awa ni omokekere ni a ngbo ise ribiribi ti awon ojise Olorun lati ilu Amerika wa nse larin awa alawodudu. Owo nla awon Amerika ti o wa nile, ti nwon ko jade si ehin odi nda fun ilosiwaju ise Olorun larin awa alawodudu ti nwon ko mo.

Kinni wa se won ti o fi je wipe awon ara Amerika yi ko nfe foju kan awon enia dudu ni ilu won ni igboro Amerika?

Mo sebi awon na ni nwon so wipe bakanna ni wa ni iwaju Olorun ti o da wa. Kini wa fa a ti nwon ko fe ri awon alawodudu ti nwon wa ni ilu won ni awujo ti nwon ba gbe wa?

Olotu, ko si nkan ti o ye awon ojise Olorun ara ilu Amerika ti nwon wa larin wa ju wipe ki nwon pada si ilu won lati ma lo se iwasu fun awon ara won ti nwon o fi ri awon enia-dudu lo. Ilu won ni ise ajihinrere tun fidi si nisisiyi nitoripe ife si enikeji ko si larin awon ara Amerika mo.

Ijero, Emi ni,

Jeremaya Aluko

Ebute-Metta

## Eto Yi Ko Dara

E jowo, e ba wa kesi awon alakoso eto eko awon omode ti ilu Eko ki nwon ba wa tun eto iforuko sile awon omode se nitori pe wahala ni eto iforuko sile na ma nmu wa lodedun.

Ni Ipinle Iwo Orun ti nwon ti da eto eko ofe sile eledun ni awon ogutogo awon obi nlo foruko awon omo won sile, wahala won ko si po to ira ti wa nilu Eko yi.

Olotu, bi e ba lo si awon ilewe ti a ti nforuko awon omo wa sile, eo ri wipe nse ni awon iya awon omo na n'lo sun sibe dojo keji Titisubu ko to wiwo lulo.

E jowo e ba wa kesi awon alakoso eto eko na ki a ma fi osu kan gbako se iforuko sile awon omo wa.

Eko Emi ni,
Alao

# Eleti-Ofe Daraba

# Balewa Fe Gbogun Ti Janduku

ENUGU — A ri irohin kan gbo lati Enugu ni Ojo Isegun ti nse eje Kedogbon osu yi wipe nigbati Olola Alhaji Abubakare Tafawa Balewa ba eko ofurufu gunle si Enugu lati ilu Eko fun ijiroro kan pelu Bale Dakita Nnamdi Azikiwe ni Nsukka nibiti o gbe nlo aye simi lowo

( Wo yoku loju ewe kejo )

# Demo Kan Tun Pade Agbako Iku Lodo Awon Janduku

IJEBU REMO—Eniti o ba ti ri awon omo ile iwe ri nibiti nwon gbe nsere idaraya lori papa pelu orin bayi pe "Ogun de bode atiro mese o le" lo le so gegeb ojo ti Ogbeni Fakunmoju ti nse okan ninu awon asiwaju egbe Demo ti se ko agbako ojo iku re lowo awon janduku egbe selu miran ni ibi aisun oku kan ni ojo Aiku to koja nigbati nwon pa si arin ona nibikan to nje Ipara ni Ijebu Remo, eleyi si ni igba keji ti won yo pa ninu awon omo egbe Demo ni arin ose kan.

Nigbati awon olopa lo gbe oku okunrin na ni titi nwon ni awon ri opol po ipa oju ada lori ati lowo re. Nwon ni ohun to fa iku ogbeni Fakunmoju ni ariyan-jiyan kan t'o besile larin on ati awon kan nibiti nwon gbe nse ariya aisun oku kan ni Ipara ni ale ojo Aiku to koja ti o si mu ija wa lehin ti awon ti pa tan nwon fi oku re sarin ona sugbon awon olopa ti gbe oku're lo si ile lakuloku ni Shagamu,

Irohin kan si a tun ri gbo lati Shagamu ni ojo Aje to koja ni awon olopa ti mu enia mefa ti nwon gbagbo pe nwon je omo egbe Alakuko ati Olope ati pe lowolowo ogunlogo awon enia ti oruko won ko ti han si agbaiye ni nwon tun ti mu ni Ago Iwoye nwon si ti ti won mole ni ogba awon olopa ni Ijebu-Ode lori esun npa iku Omoba Adepoju Odufunnade ti nse ise ile agbako ti gbogbogbo ati agbe itoju awon adie ni Ijebu Ode ni ojo Aiku to koja.

Oloye S. L. Akinola, Olotu ipinle Iwo Orun ti fi iwe ibanikedun ranse si iyawo ologbe omoba Odufunnde ni ojo Aje to koja iwe na si wi bayi pe "Irohin iku oko re to sele ninu ija buruku kan ni Ago Iwoye ni ana fun mi ni ibanuje pupo, fun emi ati awon omo egbe wa pataki yi-Demo, lori ibanikedun irin ajo ikehin ninu eyiti oko re pidanu emi re, o wu mi lati fi ibanikedun dodo okan wa tu o ninu."

"Adura wa ni pe Olorun ninu anu re tu iwo awon omo re ati gbogbo ebi omo ba na mo si fe ti emo oaju pe joba koni simi ti nwon yio fi mu awon to seka yi wa si idajo, ati pe inu mi yio dun ti o ba le jeki a mo iru eto ti nwon nse fun isin oku olufe arakunrin wa julo"

soja wa sibe k nwon wa ba won ja awon eru ti oko kan ti ko wa lati ilu oyinbo, eyiti awon osise ibe ko lati jasile, nwon si ti ko opolopo awon soja lo lati ogba soja to wa ni Idi - Oro:

Irohin nipa ise apapandodo yi de ba awon soja wonyi lati ode awon alase ile ise eti osa l'Apapa ni owuro ojo Abameta to koja nigbati nwon nse idaraya lori papa ninu ogba won, a si tun gbo pe ninu gbogbo awon eru ti nwon ja kuro ninu ko, nwon ni awon eru soja wa nibe pelu,

Nigbati iyawo awon soja wonyi gbo nipa kiko awon oko won lo sise, eru ba won, gbogbo won si pejo si baraki ti onikaluku si nwa oko tire kakiri, ati pe o ti to bi ose kan sehin ti nwon ti dase s[illegible] irewesi ni ti de ba ise eti osa, o si ju bi oko me[illegible] ati [illegible] oto akeru pelu ko[illegible] ati ekuro ninu won [illegible] nwon si wa lati o[illegible] ja eru inu won sile.

L'ose to koja, awon olopa adigbaluja kun ibe s[illegible] lati dabobo bib[illegible] awon ohun ise je, a si gbo pe enia mewa ni nwon ti mu ninu ija kan to sele larin awon ti ko sise ati awon kan ti nwon yo ise se.

Wahala ti awon ti nba lebira sise ni eti osa se lati mu ki awon oyinbo ile ise eti osa san owo yi fun awon osise won kan jasi asan ni, nitori eto yi ni ijoba se yan Oloye Okotie-Eboh lati jiroro lori re.

( Wo yoku loju ewe kejo )

BP SUPERLITE



BP

# Awon Soja Gbase Eti Osa Apapandodo L'Apapa

EKO—Oro ekunwo owo osu awon osise ti nwon nsise fun awon oyinbo oloko oju omi ti nwon wa ni eti osa ni Apapa wa di oro alagbase ati onise alagbati alagbase ni "Bi o ko ba sanwo fun mi ako ni sise fun o," tani yio je ina tani yio se omi to ma pa ina ?

Irohin yi nipa awon osise eti osa l'apapa ti awon faake kori lati sise tori won ko san ekunwo lori owo osu won fun won, ni a gbo ni ojo kerinlelogun osu yi ati wipe lori ifaka kori yi, awon alase ile ise eti osa na ti kesi ijoba lati ko awon

# Awon Minista Fe Ma Mu Ibon Rin Nitori Ija.

EKO—Ọrọ de gongo wayi ki ọlẹmọ kilọ lọmọ rẹ nitori ede ma r o, k i awọn janduku lọ sora ija ki ele-ru ma b a sun i g i nitori iroh n kan ti a tun gbọ pe laipẹ ọjọ awọn enia nla-nla larin ilu fẹ ma rin pe-lu ihamora ohun ija bi ibọn alabẹ, sekete nibikibi ti nwọn ba nlọ lati ma fi dabobo a r a w ọ n lọwọ awọn janduku enia.

Gẹgẹbi irohin na ti wi ni Ọjọ Ru to kọja a gbọ pe iru eto titun yi ni o jẹ mọ ija ti awọn janduku ngba ko a w ọ n Minista ijọba lẹnu lọọlọ yi ati pe ọpọ awọn enia ninu ilu ti nwọn npa ofin ijọba mọ ko ni anfani ati rin kiri lai pade agbako lọwọ awọn janduku wọnyi.

Nwọn n nigbati awọn Minista ba ti wa ninu ihamọra ija bayi tan agbara yio wa fun wọn lati tako ewu-kewu tabi idena awọn janduku ti ma ṣeni lọṣẹ, eleyi yio si dabi ilu agogo asọtẹlẹ ọjọ iku wọn nitoripe awọn ojọgbọn ti kiye si pe atako awọn jagidijagan wọnyi ti tan kakiri awọn ilu to w a labẹ ijọba apapọse.

# Awon Oba Fe Sofin Lori Janduku

Bakanna ni a tun g b ọ irohin lati Ibadan ni Ọjọ Iṣẹgun to kọja yi pe gbogbo awọn ọba ipinlẹ I w ọ orun ti kesi ọlọla Alhaji Abu Bakare Olotu Ijọba Apapọṣe lati pe ipade ile igbimọ aṣofin ti ijọba Apapọṣe fun ijiroro pajawiri lati ṣe ofin titun ti yio mu ki iṣesi awọn janduku pare patapata jakejado ilu ijọba apapọṣe.

Ipinnu ọrọ yi ni nwọn ṣe ninu ipade awọn ijoju gbogbo oba ni ipinlẹ na, ninu ile ọba Ọni ti ilu Ifẹ ọlọla Adesoji Aderemi ni Ibadan ni ale ojọ Iṣegun to kọja n ... s ... ki awọn olo tu ni ipinle mẹrẹrin A h ji Ahmadu Bello (Ariwa) Dọkita Michael Okpara (Ila-Orun) Oloye S. L. Akintọla (Iwọ Orun) a t i Oloye Dennis Osadebay ( Agbedemeji Iwọ orun ) ṣe ofin lori ṣ ṣe janduku Ọ m ọ-ijọka ati ainani orin ijọba ni ipinle wọn ati ori gbgba awọn janduku fun iṣẹ kiṣẹ kan L ti le fun ipinnu wọn n a gbara owọ si fi iwe K n ranṣe si Olotu Ijẹ-nlẹ I w ọ Orun, O l o y e Akintola ni ipari ipade na,

## Baba "Amugbo" F'ogorun Ponun Tanran

YABA—Ọkunrin kan, ẹni ọ d u n mejidinlogbọn ti orukọ rẹ njẹ Ojo Afọlami ni a gbọ pe awọn ọlọpa mu fun m mu ti o nmu taba "igbo" ni a r i n ilu laipe yi. Nigbati nwọn mu ọdaran na wa si kotu ke-kere to wa ni Yaba ni ọjọ Ajẹ to kọja, adajọ ni ki o lọ fi ọgọrun ponun t a n ọran ti o da tabi ko lọ ṣe-wọn oṣu mẹta ti ko ba ri owo a san.

Gẹgẹbi ọrọ ti awọn ọlọpa sọ nwọn ni Afọlami nmu taba igbo l ọ w ọ ni opopo Denton ni Ebute-Metta n gbati orun eti ta ba na ta si ọlọpa kan t o nsọde lalẹ ọjmu, ti o si wa funta pe taba tabi siga ti Afọlami nmu k i iṣe siga atata.

Lehinna ni ọlọpa to mu u wa pe lati bẹere ọ r ọ, nigbati ọlọpa na yẹ ara rẹ wo o wari daju pe t ba igbo ni o nmu lọwọ ti ... Nigbati nwọn yẹ ara re wo nwọn ba taba "IGBO" tabua ni apo sokoto rẹ.

# Aponmita



E kilo fun awon omo yin ki nwon ma se fomi sofo nidi odo mo

# Hausa Kan Ni Owo Eru Gbigba Poju L'Apapa

EKO— Ni ọjọ Iṣegun ti nṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi ni Alhaji Usman Sanka to jẹ alaga fun ile ijiroro eto lori owo ṣiṣe ni ipinlẹ Ariwa bẹ Minisita ijọba fun iṣẹ eti omi, eniti orukọ rẹ njẹ Mbazulike Amechi pe ki o lo agbara rẹ gẹgẹbi Minisita lati fi opin si gbigba owo eru ati i e ẹ eyiti o ngberu ṣiwaju ni ile iṣẹ eti ọsa ni Apapa nibiti nwọn ti nko ẹru ẹpa sọkọ ti o nlọ si ilu Oyinbo.

Ninu iwe ẹ b ẹ kan ti Hausa na kọ si Minisita na, o ni nigbati awọn moto ba ko ẹru ẹpa lati Kano wa si Apapa lati ilẹ Ariwa awọn akọwe ti nwọn nṣiṣẹ ni ile iṣẹ eti ọsa na ko ni gba ki nwọn wọ inu ọgba lọ laije pe nwọn gba owo biribiri lọwọ awọn onimoto wọnyi. O ni moto mirannduro sibẹ fun oṣu na ti nwọn ko ni da a lohun.

O ni on ti mọ anfani ni ọpọlọpọ igba lati ṣakiyesi gẹgẹbi nwọn ti i ma da awọn moto wọnyi gunlẹ ni ẹba ọna ile iṣẹ eti ọsa fun bi ọsẹ mẹrin ki nwọn to a ẹru inu wọn silẹ nitoripe oju nwọn to ni moto tabi awọn dẹrẹba moto na o ṣalẹ si ati ma fun wọn ni owo biribiri

Alhaji Usman ni iru niwa bayi jẹ n an ti yio wa pẹ titi lati mu ifile ko abuku nla ba iru ipo nla ti ilẹ Naijiria wa.

# Christian Aid Funds For Nigeria

LONDON—Nigeria is among a number of African countries which will benefit from the Christian Aid Week held in Britain in may during which over £600,000 was raised. Much of it is earmarked for African development schemes.

A sum of £4 300 is being given for rural improvement schemes in Echara £8,350 is to be used for general rural development purposes in Nigeria and £6,250 for school leavers' farms.

Chistian Aid is also supporting British Feed in From Hunger projects in providing £9,000 for farm settlements, £2000 for fertiliser demonstrations, and £2,500 as loan capital for fish e...

Altogether, Christian Aid is giving £300,000 of the money raised to the Freedom From Hunger Campaign.

During the Christian Aid Week campaign, half the houses in Britain were visited by collectors, a Salvation Army "pop" group sang beat music on the steps of St. Paul's Cathedral in London, and the Bishop of Kensington sold miniature loaves from a bread van.

## Kenya Diplomat Interviewed By BBC

Dr. J. Njuguna, Karanja, Kenya's High Commissioner in London answers questions from African journalists in this week's BBC African Service "Press Conference" which listeners can hear on Wednesday September 2 at 11. 33 GMT on 17 and 21 megacycles in the 16 and 13 metre bands.

With the conclusion so recently of the Commonwealth Prime Ministers Conference in London and the meeting of the Organisation of African Unity in Cairo it is likely that a number of extremely pertinent questions, raising vital issues in every field for the nations of Africa today, will come up for discussion.

Kenya's High Commissioner in London is a young man, only 32. Formerly a lecturer in African and Modern European History at the Royal College in Nairobi, Dr. Karanja has also studied at Makerere College in Uganda, in Delhi and at Princeton University in the United States. And this international academic background gives him a breadth of outlook which has proved invaluable as Kenya's representative in Britain.



Shermad Brown of BBC on his daily round.

## British Educationist To Tour Nigeria

LONDON — A Senior British lecturer, Mr. A.E.G P... er, of the Edinburgh University Department of Education, is to spend four weeks touring Nigeria to have discussions with teachers on objective testing—a form of testing which may help Nigeria's hard pressed examination authorities.

This will be a return visit for Mr. P...er who ... the British Council on August 31, last ... the ... Nigerian teachers and ... them about the objective testing system.

"This means that in ... part of the examination there are questions ... which only one answer is possible" he explained. "I means that the test must be very carefully constructed to avoid ambiguity and the confusion, and that the answers from the pilot scheme must be carefully studied to decide on that fairst questions. "But after that, correction is for easier and quicker process. It is absolutely standard and fair, and it releases examiners for the other part of the paper". On this tour Mr. Phillner will be visiting Lagos, Ibadan Enugu and probably a number of other centres.

Read and Advertise

IN ELETI-OFE

Your Yoruba ... exciting

Weekly Newspaper

## Awon Soja

(O bẹrẹ l' ju ewe kẹfa)

Ọgbẹni S B Bakare to je ọkan ninu awọn ọga ti ngba lebira sọfun oniwe irohin wa kan pe awọn tị pari ọrọ lori s'san ẹkunwo owo oṣu, ṣugbọn eyiti o mu ijongbọn wa ni nipa sisan owo ọya to le lori owo oṣu.

O ni 'le iṣẹ on pẹlu awọn ile iṣẹ mi ran tị nwọn nfi lebira ṣiṣẹ yio sa ipa awọn awọn lati lọ ri awọn oyinbo ọlọkọ oju omi nipa sisan ele owo ọya na, ati pe awọn si ti ṣe ọpọlọpọ ipade ẹlu wọn.

Ọgbẹni Bakare ni ko si ọrọ kan to tun le di ipinnu ti on ti ba ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ ṣe, nitoripe o n ti bẹrẹsi san owo fun awọn oṣiṣẹ ọdọ on lati oṣu keje ọdun yi.

## Balewa Fe Gbogun Ti Awon Janduku

(O bẹrẹ loju ewe kẹfa)

o sọfun awọn oniwe irohin pe on ti pinnu lati pa gbogbo iwa janduku run patapata ni ipinle Iwọ orun Naijiria, ati pe lotitọ ni on ti mura tan lati ṣe bẹ. Nigbati ọkan ninu awọn oniwe irohin na bi lere nipa nkan ti o ro lati ṣe lori iwa awọn janduku to ngbilẹ lojojumọ ni ipinlẹ Iwọ Orun o dakun pe o n lodi s imọran ti o n i w e irohin na d a lati s ọ p e ainani ofin ijọba ti ba ipinlẹ Iwọ Orun jẹ, o si wa bi oniwe iroh n na lere pada pe "Nię iwọ le sọ pe ajnaa; ofin ijọba ti ba ipinlẹ Ila Oru jẹ nitoripe awọn janduku na ajẹlẹ kan laipẹ ọ ?"

Lori ibere miran nipa irin ajo rẹ wa si Nsukka ati ajọṣepọ ẹgbẹ rẹ (NPC) pẹlu ti Alakukọ (NCNC) o ni on wa lati ba Dokita Nnamdi Azikiwe s rọ lori ọrọ ilu n i lẹhinna ẹgbẹ on ko ni ajọṣepọ kan pẹlu ẹgbẹ A'akukọ o r ẹ lasan ni awọn jọ nṣe. o n wa si ti ba ba ọkọ ofurufu p de si Eko n ọsan ọjọ kanna.

# Awon Janduku Ibadan

(O bẹrẹ loju ewe kini)

ni ọsẹ to koja ati lẹri Iferi ti Olotu Ijọba Apapọ, O l ọ t a Alhaj Tafawa Balewa ti ṣe wipe on yio ṣa gbogbo ipa on lati pa ina janduku ran ni ipinle Iwọ Orun, lo mu ki awọn ọlọpa gbogun ti wọn.

Awọn ọga Ọlọpa ni awọn ṣeṣẹ bẹrẹ ni, nwọn ni gbogbo ilu awọn janduku na ba wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun titi de Eko ni awọn yio ma kọ wọn wa si ipamọ.



Our tradition is based on principles of lasting validity; Quality in every detail, true craftsmanship applied to most advanced production methods, safety and elegant styling. The scrupulous application of these principles in the design and manufacture of all Mercedes-Benz products is manifest in the product's performance and beauty. Mercedes-Benz vehicles of today are the embodiment of a 75-year tradition of progressive development in every sphere of car design and production.



MERCEDES-BENZ

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

Printed and Published by The U... on Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street, Lagos Phone 25370; Editor, (Olotu) Ọla Onatade 15, Kosoko Street, Lagos, P O 467, Lagos.